# ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 916 LAGOS SATURDAY APRIL 19—APRIL 24 1964 KỌBỌ MEJ¡I (2D)


# Loya Oyinbo Ni Ota Awolowo Ni o Jerigbe

## O Ni Ko Jebi Rara

**EKO** — Odidi ijọ mẹrin gbako ni lọya agbẹjọro Oyinbo; Ọgbẹni Vic or Durand, ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ aṣiwaju awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹa¡fẹre (A G) ni ki ọ wa gbẹjọ on ro fi sọrọ awijare ni iwaju awọn adajọ marun wipe Awolọwọ ko jẹbi ẹjọ ti adajọ Showẹmimọ daa rara, Ọgbẹni Durand ni awọn ọta oṣelu ti nwọn nwa iṣubu rẹ ni o jẹri gbe e, ko si yẹ ki adajọ ti o gbọ ẹjọ rẹ tẹ ọrọ wọn mọ ¡ka lat fi sọọ sẹw n rara.

Ọgbẹni Durand ni ọrọ Dokita L dipọ Maja ti o fẹnu ara rẹ jẹwọ fun awọn ọlọpa wipe on ti ngbero lati fi agba ibọn fọ ile igbimọ awọn asofin ti pẹ ni o yẹ ki adajọ Showẹmimọ gbe yẹwo. O ni awọn ọlọpa ko ri iwe ẹri kan mu jade wipe owo ti Maja gba lọwọ Awolọwọ ni o ti gbaa ati pe o fi ra awọn nkan ọṣẹ fun Awolọwọ.

Agbẹjọro na ni o nfẹ ki awọn adajọ mararun fi oju amoye wo iwe kan ti awọn ọlọpa wipe Oloye Enahoro kọ, O ni Enahoro ko d ruko Oboh ati Oleari sinu iwe na rare.

(Wo iyoke ni oju ewe kẹjọ)



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

### Olotu Eleti-Ofe Atijo Jaiaisi

EKO — nu ṣe wa lati tufọ Ọgbẹni Lamoriu Ojo t¡ o fi igba kau ṣe Olotu irohin yi ni Eko ti o jalaisi ni owurọ ijẹsan ninu ¡le rẹ ni 12, Inaberi St. l'Okepopo.

Ni ọjọ kanna n¡ nwọn ṣ¡n alagba wa na, gbogbo awọn janma Mọṣalaṣ¡ Okepopo ati t¡ Ẹpẹtẹdo ni nwọn pe sibi isinku Ologbe na bamubamu pẹlu awọn ẹb¡ rẹ t¡ nwọn wa ni orile Oshodi leti Agege.

Oni ure ni Ologbe Ojo o si t¡ fi ọpọlọp ọdun se igba keji Olotu AKEDE EKO labẹ Isaac Thomas nigbati ina iwe irohin na njo l'Eko ati ni Idalẹ.

A ki ẹb¡ at¡ awọn ọmọloku nwọn ku asẹhinde, Oluwa k¡ o gbee si Afẹfẹ rere,

**EYI ARA!**

# Akowe Egbe Igbomina Kowe D'aran

EKO—A ki kọwe daran ni a gbọ, a fi ti akọwe ẹgbẹ oṣelu kan, J. G Kọlawọle Balogu , ti o nfi ¡gba kan ṣe akọwe awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọmi (NPC) ni agbegbe Ajaṣẹpo ni ẹu Ilọri ti a gbọ wipe Ad jọ kotu ganran, Ọgbẹni G s, Showẹmimọ ni ki o lọ fi ẹd - gbẹta pọnun (£500) sanran lọdọ Ọgbẹni Moses A: Ọ arenwaiu ọmọ Igbomina tiṣe minisita alamojuto eto iṣẹ awọn Ọlọpa, t¡ o pẹjọ wipe Ọgbẹni Kọlawọle Balogun pẹlu baba Ọtọtẹ, Sadiku Ayẹni t¡ o baa tẹ iwe penpe kan ni Excelsior Press fi ¡we pe pe penpe na ba on loruko jẹ.

Awọn mẹjẹji, Ọgbẹn¡ Kọlawọle Balogun ati ẹniti o ba a tẹwe na, Sadiku Ayẹn¡, ni adajọ Showẹmimọ dajọ fun w¡pe ki nwọn jọ san ẹdẹgbẹta pọnun na pẹlu pọnun marundelọgọrun (£105) owo ¡r¡n ẹse fun Ọgbẹni Ọlanrewaju na n¡toripe nwọn jẹb¡ ẹjọ t¡ nwọn gbe wa si iwaju on na.

Gẹgẹbi ẹjọ ti a gbọ ti Ọlanrewaju mu lọ si Kotu ganran, o n¡ ninu ọdun ti o kọja ni on ri ti awọn kan npin iwe afọwọ-ọjọ kan pẹlu akọle bay¡: ỌRỌ LORI OMINIRA ILẸ IGBOMINA sa kiri lọdọ awọn ara on, awọn ọmọ Igbomina t¡ nwọn wa l'Eko. Ọlanrewaju n¡ nwọn pin iwe na titi, nwọn pin de gbogbo igbe-

Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

### Orin 'Yoruba Ronu' Dofin Ni Ibadan

IBADAN – Gbogbo awọn aṣoju ti nwọn pejọ sile awọn ṣofin Ipinlẹ Iwọ Orun n¡ nwọn fẹnu kan ọrọ orin Ọgbẹni Hubert Ogunde eti orin rẹ ti o pe ni YORUBA RONU ni ijẹta nigbati Minisita alamojuto eto idajọ Ọgbẹ-Olowokofoyeku gbe iwe ofin tuutun ti nwọn fẹ ma lo fun awọn olorin awo

N¡nu ¡we ofin na a gbọ w¡pe awọn ti nwọn ba ni lati ma ṣe ere n¡ Ipinlẹ Iwọ orun ni lati ma san owo si apo Ijọba awọn ti nwọn ba si fẹ korin

( Wo oju ewe kẹjọ )

# Owo Olopa Te Dokita To Gba Riba

YABA — Awon Olopa mu Dokita kan ti oruko re nje Earnest Okeke wa si iwaju adajo ni Yaba ni ijeta pelu esun wipe ogba riba ponun marun lowo Ogbeni kan, Babatunde Falana ti awon Olopa ni o lu obinrin kan o si se e lese.

Babatunde Falana paapa ni awon olopa ko gbe si inu apoti eleri wipe ki o so tenu re bi oro na ti ri. O ni nitoto ni on pelu obinrin kan, Adetutu Bamgbose ja ni ale ojo a sun odun Keresimesi ti o koja yi.

Falana ni nigbati awon de tesan awon olopa nwon ko awon mejeji lo si ile dokita nitoripe awon fe ra pa. O ni Adetutu ni dokita na ko yewo nipa iyare re ki o to pe on paapa sodo nibu iyara re.

Falana ni Dokita Okeke ni bi on ko ba fe lo e on ki on lo wa ponun marun wa nitoripe on lu obinrin ti awon jo ja pupo, sugbon bi on ba tete wa ponun marun wa on a mo bi on a ti se oro on si.

Falana ni on be e ti o ni ko si oro ebe nibe ponun marun ni on nfe. Eleri yi ni o wa bo sita on lo sodo awon olopa u on so gbogbo re fun won o ni won si fun on ni ... un marun ti ni ... s mi si nwon si tun yan awon olopanu tele on.

Falana ni nigbati on ada de odo dokita na, Amadi olopa ti o ko awon lo lati tesan awon olopa ni on ko owo na fun, ti o si da ... si na meji loju on ki o to ko fun dokita na. Dokita Okeke paapa fun olopa na ni ponun kan soso, o ni nigbana ni dokita na wa gba pali-(card) owo on ti o ko nkankan si.

Falana ni bi on ti jade sita ni on ba ju owo si awon Olopanu wipe dokita na ti gba riba na. O ni gbara ti awon Olopanu yi wole ti nwon so fun un wipe olopanu ni awon, awon si fe ye apo re ati inu o gbe jako wo ni dokita na ti beresi logun e won lori logan.

Aniwo yi ti Dokita Okeke npa lo mu ki awon ti nba a sise sare wo iyara to awon wa, ninu won ni Noosi obinrin kan, Florence Okwuchi ti nwon ni o sare gbowo na lowo dokita ti o bo si ita ati olopa ti o mu awon ti o ja wa sodo re. Awon olopa mba awon mejeji yi sejo loto, nwon ni nwon ran dokita na lowo lati gba riba.

O di otunla ojo Aje (Monday) ki awon to ma ba ejo na lo.


E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI—OFE

ti o kun fun irohin aladun lososе.





## Awon Oni Takisi Ibadan Faake Kori

IBADAN – Gbogbo awọn Oni mọto takisi ilu Ibadan ni nwọn faake kọri wipe awọn yio di iṣẹ silẹ ni ọtunla ọjọ Aiku bi awọn alamojuto iṣẹ Ijọba ko ba tete ba awọn ṣe iki ọ fun awọn Ọlọpa ki nwọn ma gbe ofin elero mẹta ti nwọn fe gbe jade jade.

Ipade ti awọn ṣe ni Oke Mapo ni ijarun na kamama, o le ni egbaa awọn dẹrẹba Takisi ti nwọn pejọ sibẹ, olukuluku wọn ni nwọn si sọrọ wipe awọn ko ni gba aṣẹ ni umọ ti awọn olọpa Ibadan rẹ gbe jade lo awọn ero ti awọn nko lojojumọ

A gbọ wi e awọn 'ọ'ọpa ti ha awọn onimọto na ni Iwe ofi tuntun kan ninu eyiti nwọn wipe enikẹni ko gbọdọ fi mọto takisi wọn ko ero mẹrin mọ a fi ero mẹta.

Gbogbo ara Ibadan ni awọn mọ ipade awọn onimọto na lara niteripe ko si eniti e ri mọto wọ lọjọ ti nwọn nṣe ipade ra ilu Ibadan. Nwọn ni awọn a ran ikọ lo ba Oloye Akintola ki o kilọ fun awọn ọlọpa.

# Agogoro E y o, Huu–Ha–Ha !



## ARO EYO

Abẹyọ, Abẹyọ,
Abeyọ Jẹ
Kẹlẹ ọlẹ ma ṣo'lore,
Ol'ore me'wo
A bere ẹhin ?
Ẹhin wa l'ọwọ asuke e.
Asuke ti tani ? T'orisa,
Orisa ako ? T'ọmọ araye.
Ọmọ araye ako ? T'Ọlọrun,
O ma ṣe m ren mẹrẹn,
O ṣe ti'mọ t'mọ.
Ile a l'awo gbe ti wa
Gẹlẹdẹ t'ejilu ti ma'a
O fi Akala m' wo eṣ kọle
On lo lọ mu'ko Ẹleyo
Mo yọ fun e, ka yọ fun 'ra mi,
Oju ko ma se 'gi otere .
Afọnja Alagemo ki ki nse abuta,
HUU U HA HA !!

## Nigerian Studies Medical Museum Techniques



Mr. R.I. Okpa, of Lagos University, is learning a new technique of preserving anatomical organs in the museum of the Royal College of Surgeons, London. This picture shows him discussing corrosive casting with Dr. D.H. Thompsett, who is a pioneer in this technique by which acid is used to remove all flesh and so leave only the veins and arteries.

These organs are then available for training doctors. "This museum is probably the [illegible] in the world" said Mr. Okpa, who is Tutor Prosector of Anatomy. "There is nothing else to compare with it and people from medical schools all over the globe are constantly visiting it for advice".

After a six months course, which includes display and cataloguing, Mr Okpa hopes to set up a full scale medical museum when he returns to Nigeria.

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI–OFE ti o kun fun irohin aladun losose.

# ELETI-OFE

(A NJU W N KO ŞE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV: NO 917 SATURDAY April 18—April 24 1964


## ORO OLOTU:

# Inakuna Owo Ijoba.

Ọpọlọpọ alamu ni awọn dọbalẹ, sugbọn a ko mọ eyiti iau orun gbogbo wọn. Ni ojojumọ ni a agbọ iri hi lati gbogbo Ipinlẹ Ijọba Nigeria wipe awọn akọwe ile şe Ijọba poora owo tabi ki awọn lu owo Ijob i poapo ni ọna ti ko ba oju mu.

Şe a gbọ wipe egungun ti a ba so maja lọrun ko gbọdọ san an ş gbọn nisisiyi awon ja gbowo-mi-gbo om gbe owo Ijọba m nis s y lajsi ifoya

Ọrọ na w. dabi rọ tani le mu mi ti mo ba na owo Ijoba lọ a ti o wu mi. Nitoto i n le ma wọ ?

Oni a gbọ wipe awọ akọwe Ijoba kan o o vo-ori je, ọla gbọ wi e awon ọga iṣẹ ile Ijoba kan ko g ogi moto Ijọb ta; ọtunla a gbọ wipe awon a a-kọs Ijọba kan ra ọrakura ile ati i ẹ fun Ij ba l e ti o ju gba pọun lọk a san bi ẹg n m dogun pọ un f n un.

Ẹnyin ọkawe wa, awa Eleti-Ọfẹ ko le ri ki a ma so, INAKUNA AWỌN ALAMOJUTO IJỌBA wa pọ pupọ ju, awọ Oyinbo ko na owo wa bayi nigbati a wa labẹ wọn.

Bi a ko ba fẹ ma ya owo kiri nilu ajoji, o yẹ ki a ma sun owo awọn ara ilu na nit rire egungun ti a so mọ aja lọrun ni ko yẹ ki aja ko s n an.

# Aboyun Kan Ya Irinwo Aran

ABA — Aboyun kan ọmọ ilu kan ti nwọn npe ni Ikot Ekpene lati Kalaba ni a gbọ wipe o ya irinwo aran nigbati awọn ru u wa si ile awọn alamodi kan ti nwọn npe ni Marcus Mọmorial Hospital ni Aba nibi.

A gbọ wipe şe abẹ ni Dokita ti o wo aboyun na şe fun un ki o to ko awọn aran na jade ninu rẹ. Awọn ara na gun to nşi mẹfa ni şobọlọşobọlọ, enu wọn si mu şonşo bi abẹrẹ.

Oyun oşu mẹrin ni o wa ninu obinrin na.

# Iwe Si Olotu

# Owo Ile Kamama L'Eko

Ẹ jọwọ ẹ ba wa kesi awọn Olotu Ijọba wa ki nwọn şe ofin owo ile mehaya ti nwọn mbu owo si lojojumọ ni ilu Eko. A gbọ nigba kan wipe awọn asofin ni ile igbimọ ti gbenu le ọrọ na wipe awọn fẹ sofin ki iya ma le jẹ mehaya mọ, sugbọn a ko mọ nkan ti o tun nfa wọn sẹhin:

Boya o lejẹ wipe nitoripe gbogbo awọn ikọ wa ti nwọn wa nile igbimọ ti nwọn kọ ile ni nwọn nkilọ fun awọn ara wọn wipe ki nwọn ju ọrọ na sile ile soro kọ.

Bi awọn alamojuto Ijọba wa ba nfẹ idẹra fun ara ilu o yẹ ki nwọn ba wa fi ofin de owo ile gbigbe ti a nhaya mọlẹ. Aşeju awọn onile pọ ju Olotu.

Emi ni,
O. Adeleke
Shọfuntere,
Ebute—Mẹtta

## Iwa Won Ni..

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati kin Ọgbẹni Olasupọ Adigun lẹhin fun iwe rẹ ti o kọ bere wipe kini mba awọn alakoso Ijọba lẹru ti nwọn fi nfi ofin ki onile gbele se wa mọ nigbagbogbo.

Ko si nkan ti o mba wọn lẹru ju iwa wọn lọ; nitotọ iwa ọmọ ni mu ọmọ şe oogun okigbẹ.

Nkan ti o tun nya ọpọlọpọ wa lẹnu nipa ofin wọn na ni wipe awọn ti o npaşẹ ofin na, awọn na ni awọn si nru wọn.

Olotu, ọrọ na ko ba oju mu rara, awa na si ti mọ nisisiyi wipe iwa wọn ni o mba wọn lẹru,

Isale Eko, Emi ni,
Eko Layi Ajagbe

## Iwa Lesin ...

Mo gbadun ọrọ ti Olotu sọ fun awọn ero ti nwọn nlo si ilu Mẹka ọdọdun lati ilu wa wipe ọrọ Mẹka tabi a npe ni Alhaji kişe ki a ma lọ si Mẹka nigbagbogbo bikoşe ki a toju iwa wa.

Alagba, ẹlẹsin Jesu ni emi, nko si nfi oju tinrin awọn Imale ti o ba jẹ oni gbagbọ ododo, nitoripe opolọpọ eniyan ni awọn wa larin eles n Jesu ati ti Mọmọdu ti iwa wọn buruju ti awọn abọrşa lọ.

Mo mọ opolọpọ awọn ti a npe ni Alhaji ti iwa ko jọ onijibiti oniwayọ, alọmlọwọgba ati ọlọşa ni nwọn nhu kiri Emi mọ nkankan daju— yẹn ni wipe IWA LẸSIN iwa ni yio gbe onịwa bi o ba de ọrun, ero Mẹka ẹ şe pẹlẹ.

Emi ni
Luku Ọmọlere
Ojo Street,
Mushin

## Pipa Ni Ole?

Mo gbọ iroh ni u ẹrọ redio ni ana ti awọn agba ọşelu ju wa nda a laba wi e ki awọn alaşẹ şe ofin kan ti nwọn a ma fi pa awọn ole ọlọşa ti awọn ọlọpa ba ri mu.

Ẹ jọwọ ol tu, emi na fi ara mọ aba wọn na ọlọşa ti o wọle wa ba wa ni igunjọ eru ko ro nkan rere si wa. Bi enia ba taji lojiji ti o fẹ mu u yio gun oluwarẹ ọbẹ ninu.

Nigbati awọn ọmọ jaguda, ti nwọn nyọ owo lapo ero nşe lo yẹ ki nwọn ma ge wọn lọwọ, ẹnikẹni ti o ba ti de ọdọ ọlọpa ni ẹmeji fun ẹsun jaguda.

Eleyi a jẹki awọn ole dinku nilu. Olotu, mo fara mọ aba awọnagba oşelu na.

Emi ni,
Rabiu Alao
Kọrọ Agbẹdẹ,
Eko

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

Lati Owo Ayiluka

# Alhaji Adegbenro Ni Ojo Idibo Ku Si Dede

IBADAN — Alhaji D S Adegbonro, Igba keji aş waju awọn ọmọ ẹgbẹ Ọ̣ọpẹ (AG) i rogbodiyan ti o bẹsi si ni idsata ni Ipinlẹ Iwọ Oran dabi ẹnipe awọn ọmọ ẹgbẹ awọn ni rogbodiyan na gbe nitori o jẹki awọn tete mọ awọn alagabangebe ti nwọn wa ninu gbẹ awọn.

Ni papa Resi (Race Course) ni Ibadan ni Alhaji Adegbenro ti sọ,o yi ninu ọsẹ yi nigbati o mba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ sọrọ nibi apejọ kini ti nw n yio kọ şe lẹhin ti da ijangbọn na silẹ ninn ile gbimọ aşofin.

Alhaji Adegbenro si awọn ọmọ ẹgbẹ o ọ ni nwọn kọgbọn ninu rogbodiyan na, awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) paapa kọ ọpọlọp ogbọn ninu rogbodiyan na.



Alhaji D S Adegbenro

O ni o jẹki awọn ba mọ wipe agbajọ ọwọ ni a fi nsọ aya. O n i didapọ ti awọn ẹgbẹ mejeji jọ fẹ da ajọşepọ yi nfi awọn ara ilu lọkan alẹ wipe ireti nla mbọ fun awọn.

O ni gbogbo ilu ni n ọn mọ wipe lati ọjọ ti ijangbọn ti bẹ silẹ ni awọn ara ilu paapa ke ti ri owo na to bẹ mọ.

Alhaji Adegbenro ni on fẹ ki awọn ara ilu mọ nkankan nkan na ni wipe ni ajiji ni awọn i o n e eto Ijọba ni Ibadan nis yi yio tu ile igbimọ ka, ti nwọn yio wipe ki awọn wa dibo ni orina ki gbogbo wọn lọ mura silẹ, ki awọn si duro giri bi akọn enia nitoripe ko si nkan ti e mbọ ti ọna ko gba.

# Ina Jo Ni Isale Eko

EKO — Ina nla kan ti o jo ni Isalẹ Eko ni oru ọjọ ọsẹ şe awọn ara adugbo ti nwọn npe ni Onilẹgbalẹ lofo pupọ; a gbọ wipe o ju ag o ile mẹtadinl gun lọ ti ina na jo bolẹ patapata.

Gẹgebi irohin ti a gbọ nipa I a na, awọn ara adugbo ni obinrin kan ni o ndin ẹja ti o gbagbe lati pa ina ti o fi nọin ninu 'di aro ki o to lọ sun; lẹhin eyi ni ina ba gbele ti o ta mọ ọpa ati ninu ile.

Ki awọn panapana to sare de Isale Eko nibiti ina na gbe nj o ti ba nkan jẹ fun awọn ara adugbo. Ọpọlọpọ awọn ouile na u nwọu k tiẹ si ie nigbati ua na bẹrẹ.

Ọmọ Onilegbale kan ti nwọn npe ni J mọ ni gbogbo eru on ati ti awọn iyawo on m rerin ni ina so di eru patapata, o ni fi a on ko r mejide nigbat on si duro ninu iyara ti on nsun lowọ.

DAGENITE
BATTERIES
give you a longer run for your money!





Eleti-Ofe Daraba

# Arun Yapayapa De!

## Lati Owo Olofintoto

Bi enia ba pe pupo ninu aiye ti awa yi oju Oluwa re a ri irikuri. Lehin ogun ajakaiye, ni iwon nkan ni odun mejidinlogoji, ajakale arun kan ba gbogbo araiye ja ti gbogbo wa fun ni oruko bayi 'LUKU LUKU' sugbon suna ti awon Oyinbo fun arun na ni Influenza. Arun yi tomode tagba ni o ba ja, oke aimoye enia ni o si pa bamubamu lehin ogun ajakaiye yi. Awon ogunagbongbo dokita igba na ni egbogi oloro kan ti awon Oyinba Jamani (German) lo lati fi ja ogun nigba a ni fa arun yi.

### Aiye Nlo

Bi amodi luku-luku yi ba ba enia lori irin ni ita gbangba o di ki oluware fi orun kole ki o ma poka iku. Enikeni ti o ba ti fole ti mo wipe on ti gba ojo iku niyen a fi enliti Olorun ba yo.

Lehin eyi ninu ogun agbaiye keji ti awon a a gbara sese ja tan, awo Oyinbo ologun tun wa e.u iwon olor kan ri ti nwon npe ni atomic bomb. Ibikibi ti nwon ba gbe fo etu-ibon na s di ibi egbe, o di ibi iparun. Gbogbo ara ilu na, ati eranko pelu ohun ogbin a parc patapata. Awon ti Olorun ba da si koni je enia mo.

### A Nto o

Nwon a pa lori bi eiye igun. Awon okunri a di akura, awon k ni le ba obinrin lo po mo; awon obinrin a di agan, nwon ni le loyun m . Ibi ti ategun re ba fe lo (bi ira bi a i si Kano) awon hra e pade agbako ni-yen.

Nkan buruku ti nwon ko je, ti nwon fi se etu-ibon oloro yi awon alagbara na ni o ye nitorina ni gbogbo awonara aiye se pa ohun po ti awon mbe won wipe ki nwo ye dan etu-ibon oloro na wo nibikibi mo.

### Yapayapa De!

Eyiti o tun pabambari ni egbogi kan ti mo gbo wipe awon ara ilu Oyinbo fi ake kori wipe awon ko ni lo o fun awon aboyun mo; nwon npe oruko egbogi na ni THALIDO MIDE. Opolopo awon omotuntun ti iya won lo egbogi yi ninu oyun n tori ki nwon ba le bi pelu irora ni nwon bi ibikubi kale.

Mo gbo wipe ninu osu to koja y i e awon obinrin omo ti awon ni ilu Oyinbo ti nwon ko ni pa ti nwon ko le je nkan bi edegberin (700) enia. Iye Iye ru awon abami omo be ti won yio tun bi ninu o u yi a lo t mo. Nwon ni egbogi buruku yi ni o la awon omo ibkubi yi

Nino ese ti o koja yi ri Oyinbo a atede kan ti o loy n t d kna re si ti lo egbogi jebebi (Thalidomide) yi fun

(Wo yoku loju ewe kejo)

# Keji Olowoele Fowo Tanran

ILE 'FE—Adajo agba, Ogbeni Akin Delumo, pase wipe ki baba agbe kan, John Keji ti o nya awon egbe re ni owo ele fi pon-un me adinlogoji o din sile marun tanran fun owo ele ti o nya awon enia ti ko gba iwe se lodo Ijoba.

Awon agbe mokanla kan ti odaran na nya lowo pelu ele gobiyi lori owo na ni nwon wo Keji wa si kotu lati abule re ni Akiriboto leti Gboongan; nwon ni omo egbe Igbimo awon agbe Iwo Orun ni awon.

Nwon ni Keji nya awon agbe na lowo, o si mbu ele si i kobọyi, owo ele ti o mbu si owo re na po tobege ti opolopo ki le san an.

Odaran na se alaye fun adajo wipe nse ni on nfi owo na se awon agbe na ni anu gegebi asa awa Yoruba, on ko fi owo yiya se ise rara.

# Eleti-Ofe Daraba

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba jepe Kerosine lo fe BP Superlite Fayo o le ri rà nibikibi, ko si wọn, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mã fi yàná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

# BCGA Discuss Nigeria's Cotton Industry

LONDON — The rapid and successful developmen of the cotton indnstry in Nigeria was discussed at the annual meeting in Marchester of the British Cotton Growing Associaion by their President, the Earl of Derby, last weekend.

The Nigerian cotton ginned out at over 280,000 bales and came close to exceeding the highest ever production, Lord Derby reported.

'Excellent out-turns were obtained from the factories and a preudetion recod of 16,532 bales in a week was established, 'he said.

Increases in the growth of American types of cotton in nearly all the African countries during the year, including 122 000 bales in Nigeria, gave a net overall production increase of 85 000 bales, waile total production rose to a new record of 1 935 200 bales

Nigeria's own textile industry was now taking a substantial production of the local crop, Lord Darby went on; as more mills were projected in Nigeria, it was obvious that intensive efforts would have to be made to increase production if exports were to be maintained.

High proces were undoubtedly the best stimulus but much could be done by encouraging farmers to adopt new and the scientific progress that had been made in recent years.

The Nigerian industry's chief need at present was better methods of cultivation, taking advantage of for more extension workers in ths field to instruct local farmers in the best methons of cultivation and where necessary in said Lord Derby.

## Disarmament Delegation

LONDON— Sir Harold Beeley, the present British Ambassador at Cairo, is being appointed perminet British representative to the Disarmament Conference, Geneva, in succession to Sir Paul Mason, who is retiring from the Foreign Service.

Sir George Middleton, at present Ambssador at Buenos Aires, is to succeed Sir Harold in Cairo.

# British Writer On The Beauty Of Abuja Pottery

LONDON—The beauty of Abuja pottery, the artistry of the Nigerian potters trained there and the value of their work in stimulating craftsmen all over the world, is the subject of a two-page article by Jonathan Siye in the April edition of AFRICAN WORLD.

Pictures of the Training Centre, of its founder Michael Cardew the Cornish potter and of Ladi Kwali, M. B. E., its most famous trainee whose work has been bought by museums in Britain Europe and America illustrate the article tracing the history of the Abuja Centre, which says Slye, has now been successful in relating modern to traditional methods. 'And it can be reasonably predicted that it will in the future not only enrich rural potters' work but prevent it as a craft from perishing in the flood of imported, unartistic metal and enamel substitutes' he observes.

Abuja products, he goes on are 'universally acclaimed by connoisseurs of the ceramic world. Examples stand on the shelves of private collectors, the Victoria and Albert Museum, London, Bornan's Museum, R[illegible] Harman Foundation New York and in Nigerian Embass es throughout the world.

## British Ship On Maden Voyage To West Africa

LONDON—A new British cargo ship built for Elder Dempster Lines, the m. v. 'Fian' sai her maiden voyage from Liverpool on April 16 to a number of West African ports, including Lagos and Calabar

The 'Fian' named after the town in [illegible] Province, Northern Ghana was under the command of Captain N. Pryce. Her crew consists of men from Britain and Sierra Leone totalling forty-five.

The 'Fian' was built by Messrs Lithgow of Port Glasgow and was launched last October. She is the final vessel [illegible] series of six [illegible] design, meeting the [illegible] requirements of the West African trade.

She will operate at a service speed of 16 knots propelled by a single screw driven by a Fairfield-Sulzer diesel of 7500 bhp.

The [illegible] ports of call on her maiden voyage include Dakar, Bathurst, Takoradi, Cotonou, Tiko, Douala, Santa Isabel e, Point Noire and Fernando Po.


## LAGOS RACE CLUB

A Special Race Meeting will take place on Sunday 19th April, 1964. First Race at 3.30 p m.

Sweepstake will be drawn on the number of Admission Tickets. 1st will be paid £2. 10/-, 2nd £1. 10/- and 3rd 10/-.

Hon. SECRETARY
LAGOS RACE CLUB.


# Eleti-Ofe D'araba

# Loya Oyinbo Ni a Awolowo

(O bere ni oju ewe kinni)

o ni oro nipa awon akowe egbe won ti nwon osise fun egbe Afenifere ni agbede meji Ijoba I w o orun nigbana ni o Enahoro mbere wipe se ki on san owo asanle kan fun won.

Agbejoro Oyinbo na ni Enahoro pelu aduru iwe ti o m o k o le fun enia lowo t a n, ki o tu m a bere wipe se ki on s a n owo asanle fun won.

O ni nigbati awon tile nso wipe loju Oba Ile Ife ni Oloye Awolowo ti nleri wipe on ni awon enia ti nwon le ki Ijoba Apapose wo ti nwon ba fe se yanpon yanpon; agbejoro Oyinbo na ni eto adajo Showemimo i wipe ki o fi iwe pe Oba Aderemi ki o wa gbo tenu re ko y e ki o gbo tenu ika dajo.

Agbejoro na ni ota ponmoyan ni awon O l o y e Duro Ogundiran, Oshuntokun Dokita Onabamiro pelu awon Alhaji Ibrahim Imam ati Patrick Dokotri ti nwon ti ya kuro ninu egbe Awolowo.

O ni Alhaji Imam ati Dokotri ni awon ti kuro ninu egbe Afenifere (AG) tipe ninu egbe U P P ni awon Ogundiran Oshuntokun ati Onabamiro si wa nigbati nwon wa si kotu lati wa jeri. Agbejoro na ni ko ye on rara bawo ni adajo Showemimo se ro oro na ti o fi wa so wipe omo egbe Afenifere (AG) ni nwon on ko si lero wipe awon omo eg e Afenifere na si le wa jeri oke g e as aju egbe won.

O ni iru ero bayi ni adajo Showemimo fi si ara re lona patapata ki o to so Oloye Awolowo sewon odun mewa.

Loya Oyinbo na ti enia buruku ni Dokita Ladipo Maja enit a ri, ti a si fun si ni to ye ki adajo ti o se ejo wolowo gbero re gbo rara.

Loya Oh ...y ola ni o si mba awijare tiro ol ri oro awon Asp Akinmoya, S. T. Oyede n, L. K. Jakande Sinmen Oyesile pelu J. O. Lawason.

# Ere Eyo Ko Bosi Mo

EKO—Ere ti a so wipe adao G B A Coker fe ki nwon se ni ojo Abameta (Saturday) ojo meio loni ni Eko fun Ologbe baba re ko bosi mo, nwon ti ye e si igba miran sugbon nwon ko fi ojo si i.

Gegebi irohin ti a gbo, a gbo wipe okuta kan ti nwon fe lo ni oju oriri oku na ti ko de lati ilu Oyinbo ni o fa sababi y ye ere eoo na, sugbon a ti te ARO EYO fun yin loju ewe keta ninu iwe yi.

# Akowe Egbe

(O bere loju ewe kinni)

riko Ilorin ati ile Igbomina nibiti nwon gbe ti dibo fun on wole Igbimo awon asofin.

Olanrewaju ni ko si nkan ti nwon ko fi on we t n ninu iwe kekere na; nwon ni o ko m' oi i si oro ominira ile Igbomina i nwon so wipe awon nfe ki Ijoba Ilorin yan Ijoba ibile ti awon fun awon, ati pe on ko tile ye ri enii nwon ni lati yan fun i e osolu rara.

O ni oro inu iwe na se on ni kayefi nitoripe oju enia lasan ni awon enia on fin wo on lati igbana wa, on ko je ara ile, ara ode.

Egba medogbon (£50,000) ni owo ti Ogbeni Olanrewaju ni on fe ki adajo ko ba on gba lowo Ogbeni Kolawole Balogun ti o kowe na ati Sadiku Ayeni-ti o ba a te iwe na ki adajo to din owo itanran na si edegbeta ponun (£500) saraji. Owo irin ese ti o kun un ni o ieki gbogbo owo na di ponun marun o le ni egbeta (£605) ti awon mejeji ni lati fi tanran.

# Orin "Yoruba Ronu' Dofin Ni Ibadan

(O bere loju ewe kini)

si owo rekodi ni lati ma fi han awon olopa ki nwon to gbe jade.

Alhaji Adegbenro tako ofin na, o ni nitori ere YORUBA RONU ti Ogbeni Oguude gbe jade ni o ngun awon alamojuto Ijoba lara, Alhaji Adegbenro ni ofin na ko ba oju mu rara ona ti ijoba le gba rowo wa loto.


**Never**

refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos, Phone 23310; Editor, (Ol tu) O a Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467.